## A fẹ ki Irohin Yoruba ma a jade lojojumọ

E JỌWỌ gba mi laye lati sọ pe mo ti ara mọ aba ti Ọgọẹni R. Lawal ti o wa ni ilu Maiduguri da pe, ki iwe "Irohin Yoruba" ma a jade lojojumọ gẹgẹbi awọn iwe irohin ojojumọ ti njade ni ede Gẹẹsi.

Awa ti ko mọ iwe l'ede Gẹẹsi ka ni anfani lati mọ ohun ti o nlọ ni aiye paapa ni ilu wa Naijiria nipa kika "Irohin Yoruba". A si ni itara lati fẹ ma a mọ ohun ti o nlọ kakiri ilu lojojumọ. Bi ko bai ti si aye pe ki iwe na ma a jade lojojumọ, ẹ jẹki o ma a jade lẹmeji losẹosẹ.

A dupẹ o.

YAKUBU AYINDE.
Ibadan.

## Iwe si Olotu Irohin Yoruba

## T'Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ọmọ Ilọrin Owode nṣe

E JỌWỌ, ẹ gba mi l'aye lati ṣe alaye yi fun awọn ara mi. Iba alaye na niyi:—Nigbati a bẹrẹ Ẹgbẹ Talaka dapo-mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Owode yi mo ri daju-daju pe orisirisi anfani ni o wa fun awa ọmọ Ilọrin to wa ni ilu yi.

Alaga wa, Alhaji Sule Ayinla, ti iṣe Alakoso Ẹgbẹ Talaka Parapọ ti ọpọlọ rẹ pe ṣaṣa si tun ṣe alaye fun awa ọmọ Ilọrin to wa ni ilu yi pe a ko gbọdọ gba ẹgbẹ buruku miran kan laye l'rin wa. Ati pe on ro ori wo dada, on si ri pe Ẹgbẹ Afẹnifẹre nikan lo nṣe ododo ni Naijiria.

O si tun sọ pe o yẹ ki a kiyesi pe, gbogbo ibo ti nwọn tun di ni ilẹ Ẹgba ati awọn ilu miran bẹẹbẹẹ ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Ẹgbẹ Afẹifẹre (Action Group) lo tun bori bakanna fun ododo wọn. Bakanna ni Alfa Shehu Dan Imama ṣe alaye fun wa pe, gbogbo wa ni lati di Ẹgbẹ Afẹnifẹre mu daada ki ilọsiwaju le wa fun wa dada ninu eto iṣelu wa.

Ki Oluwa maṣe tu wa ka o! Amin. Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi. Ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o! Amin. Waju ni ẹ o ma a lọ gẹgẹbi orukọ mi.

B. A. ALIYU ỌLANREWAJU
**Akọwe Ẹgbẹ Talaka Parapọ dapọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre.**
Owode-Abẹokuta.

## Ọmọ Shaki, ẹ pada lẹhin Ẹgbẹ Alakukọ

E JỌWỌ mo bẹ l'ọmọde t'agba ilu Shaki ki ẹ fi Ibaralẹ gbọ imọran mi yi. imọran mi na nipe ki a jawọ kuro ninu Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ki ilu wa le ni idagbasoke bi ti awọn ilu yoku ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) nṣe alakoso Igbimọ Ijọba Ibilẹ wọn.

Ṣe ẹnyin na ti ka ninu Iwe Ijapa pe: "Tani o gọ bi ọmọ akukọ yi?" o tọ, o si yẹ ki ilu Shaki jawọ kuro ninu Ẹgbẹ Alakukọ. Itiju nla ni fun awa ọmọ Shaki ti a wa l'Oke-Okun lati ma a gbọ pe Ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn joye fọ'le fọ'lu ni Ibadan ni o nṣe Alakoso Igbimọ Ijọba Ibilẹ wa.

E jẹki a ronupiwada fun ire ilu wa, nitori awọn ọmọ wa ti yio di opo ilu mu ni ẹhin ola ma ba a ba wa ninu Ẹgbẹ "Tani o gọ bi ọmọ akukọ yi?"

Emi ni,
E'LIJAH ABIỌLA.
Ghana.

## Imọran pataki fun igbimọ L.E.D.B.

E JỌWỌ, ẹ gba mi laye ninu Iwe nyin lati fun awọn Igbimọ Atunlu-Eko -ṣe (Lags Executive Development Board) ni imọran ti yio ṣe Igbimọ na ati awọn ara ilu Eko ti nwọn ti gba ile wọn na ni anfani.

Idi ti mo fi fẹ lati fun wọn ni imọran na ni pe awọn ti nwọn ti gba ile wọn ni ikunsinu si wọn pe: laseko ti awọn Igbimọ na ba fẹ gba ile awọn nṣe ni nwọn npara lọdọ awọn nigbakugba. Ṣugbọn lẹhinti nwọn ba ti gba a tan, nwon ko ni san owo ile (compensation) na laseko. Nwon a kan ma a gbe awọn paara, nwọn a ma da oni, da ọla titi suuru awọn yio fi pin. Eyi ni o ngmu awọn miran fi gba lọya ti nwọn. Bẹ ẹ inira ni fun wa lati tun ma a san owo lọya ninu owo iwon iba ti nwọn o fun awọn onile na.

A bẹ awọn Igbimọ na, paapa awọn ti nwọn nṣe eto ile na (Valuation Officers) ki nwọn tete ma a san owo ile wọn fun wọn, ki wọn ye gbe wọn paara mọ, ki nwọn si san iye ti ile wọn ba to. A bẹ Ọlọla Kofo Abayọmi, Alaga Igbimọ na ti a fi ọkan balẹ si lati ṣe atunṣe laseko.

A dupẹ o.

Y. AYINLA DISU.
Eko

## Iwere-Ile nfẹ iranlọwọ Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre

AWA ọmọ ilu Iwere-Ile dupẹ lọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) fun iṣẹ ribiribi ti nwon ṣe yika Ipinlẹ Iwọ-Orun. Awọn enia ti o ba ntapa si Ijọba Ẹgbẹ yi jẹ alaimore enia ni.

A dupe lọwọ Olotu iwe "Irohin Yoruba" fun irohin ti o nfun gbogbo ara Ipinlẹ Iwọ-Orun nipa Ẹgbẹ rere yi nigbagbogbo. Irohin na maa nfun wa ni inu didun pupọ, ki Ọlọrun jẹki owo nyin ma a lọ soke nipa ṣiṣe iru iṣẹ rere bayi. Amin.

A bẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ki nwọn ba wa tun Odo Ofiki ti o wa ni arin Iganna si Iwere-Ileṣe ati Odo Ọyan ti o wa larin Iwere-Ile si Ijio na ṣe pẹlu; nitori pe awọn odo wọnyi nda awọn onisowo wa duro ni akoko ojo. O si ngmu irẹsilẹ ba gbogbo ilu ati awọn ti o wa ni agbegbe rẹ bakanna pẹlu.

Ki ẹ jọwọ, a bẹ nyin gidigidi ki ẹ tete ba wa mu oju to awọn odo na. Ọlọrun yio ma a ran nyin lọwọ siwaju ati siwaju o.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi. Ọlọrun ko ni jẹki ọkọ Oba ki o ṣa nyin lẹsẹ o. Amin.

Emi ni,
DANIEL ADE ỌMỌTỌSHỌ.








SUNLIGHT
dię nfọ
ọpọlọpọ aṣọ

Ege Sunlight nla kan a mā fọ ọpọlọpọ aṣọ. O ni alopẹ, o si ndin inawo ku. Sa da awọn aṣọ nā si omi, fi Sunlight fọ nwọn, wa ri hibo atata ati bi nwọn yio ti mọ to. Sunlight tun le pẹlu, o dara fun itọju awọ ara, o si ni orun ti o dara pupọ.

*Ni Nigeria ni a ti nṣe e.*



Ọṣẹ SUNLIGHT
—ni o dara julo ni wiwe

